Chief Secretary the Govmt

# EKO AKETE.

"Emi \io fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. VI. No 2?6. SATURDAY, OCTOBER 13, 1928 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

CHIEF SECRETARY'S OFFICE 18 OCT. 192[8] LAGOS


## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nje ki o ri aye wu arun mi silẹ.


Akin ... [signature]

LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
Dr Earl Sloan




TO STOP
YOUR ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale: Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd. London Eng.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

ARUN MBẸ, AWA EKO.

Kiku ti awọn enia nku ni oporopo ni ẹnu ọse kan to kọja yi wa ko ni ṣai da ẹnikẹni niji pe arun ti Ayọkẹlẹ mbẹ ni igboro Eko ninu ọsẹ tokọja yi ni a gbọ pe awọn igiripa kọnrin meji fo ṣanlẹ ku ni ẹnu ọjọ diẹ si ara wọn.

Ọgbẹni Barreto jalaisi ni *Sunday* tokọja lẹhin amodi ọjọ bi marun, bẹ si ni Ọgbẹni kan jalaisi ni Oju oto lẹhin aisan ọjọ melokan.

IGARA OKO NPELE SI LOJOJUMỌ.

A gbọ pe awọn igara ti tun bẹrẹ si gbe sunmọmi kakiri oko oloko ni gbogbo igberiko Agege Alagbado ati awọn ilu kekeke miran tobẹ ti a fi gbọ pe ẹnikan tilẹ tile tọna ra ẹtu ibọn fun ati ma yin ninu abule rẹ fun idabobo ara rẹ ati awọn enia rẹ pẹlu—gbogbo ikan wọnyi nṣẹlẹ labẹ ofin gesi. Eyitijẹ?

DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

MỌGAJI OPE.

Gbukẹ li a gbọ ti iku Ọgbẹni Abudu Lasisi Mọgaji Ope ti Ẹpẹtẹdo ni ọjọ Jimọ ijẹsan—nwọn sin oku rẹ si itẹ Oke Suna, a ki Sẹliya Ope, Sanni Ope—awọn arota dede ati awọn ọmọ-loku iyoku nwọn ku ọfọ o, ẹhin rẹ yio dara o!

IPADE IṢẸGUN.

Awọn ẹgbẹ Dẹmọ ṣe ipade iṣẹgun wọn ni ọjọ Satide ti o kọja ọjọ kẹfa oṣu yi, fun ayọ ibo wọn ti nwọn di ni ọjọ *September 28, 1928*, fun awọn mẹta ti ilu yan ( Jones, Moore ati Doherty ) ti nwọn si wọ ile; bẹni ki a ma ri.

"ADANILORO FI AGBARA KỌ NI."

Ọrọ oke yi ni oriki ti Ọgbẹni Shacoleford ẹniti o rọpo Alaga Ọlọla Moore fun ẹgbẹ Dẹmọ ni ajọ ti nwọn ṣe kọja ( 6 October 1928,) nigbati yio fi pari oro rẹ gẹgẹ bi Alaga gbogbo ọmọ-ẹgbẹ si ni awọn gba oriki na, njẹ Dẹmọ gba Suna titun na dipo "Dọmọ" ti ẹnikan ni on sọ ẹgbẹ na nijosi ni gasikiya "Adaniloro fi agbara kọ ni."

ỌGBẸNI VICTOR BABAMUBỌNI.

Ọgbẹni yi sọrọ ni ipade ẹgbẹ Dẹmọ na awọn diẹ ninu awọn ọrọ rẹ ti o sọ ni iwọnyi :—

Mo ki gbogbo nyin patapata, mo ti ni ọrọ diẹ nilẹ lati sọ si eti igbọ ẹgbẹ, ṣugbọn mo ti lọ si idalẹ ni lọlọyi.

Gbogbo wa ti a mbẹ nihin loni yi, Onigbagbọ mbẹ ninu wa, Imale mbẹ ninu wa, awọn ti o tun ṣikẹta ni awọn Keferi ṣugbọn nwọn ko to nkan, ki e wo isin igbagbọ nigbati o dide inunibini pọ fun wọn, bẹni o si mbẹ fun isin Imale papa pẹlu, awọn ti o nṣe inunibini si wọn nigbana nwọn ko ṣe ohun buburu loju wa, nitori pe nwọn tunbọ ngbe soke ni, bẹni o si mbẹ fun ẹgbẹ yi, nigbati nwọn da silẹ ni ọdun karun, ọta pọ fun ẹgbẹ na ti nwọn nditẹ si i ṣugbọn a nkigbe wipe nwọn nditẹ si i, bi nwọn ko ba ditẹ si i kole lọ si oke bayi, ko le fi idi mulẹ bayi.

Emi iṣẹ Iwe-irohin ( *Daily News* ) ni mo nṣe o si ti ni iye anfani ti iwe na tiṣe fun wa ni ilu yi, nitori ko si iwe-irohin wa ti o dabi rẹ, o nfun wa ni oye gbogbo bi nkan ti nlọ si larin ilu.

A nka awọn iwe-irohin gbogbo ti o nti iwaju wa, a si nri gbogbo nkan ti nwọn nṣe.

Mo ro wipe ẹ ranti Ọgbẹni Makọli nipa ayan rẹ ti o ṣe nipasẹ ọrọ ilẹ Apapa ti Oloye Oluwa, lori gbogbo wahala ti Makọli ṣe sidi ọran ilẹ na, ko ni ẹsẹ bata kan nibẹ, awọn ti nwọn mu ni ọta omiran njẹ anfani ilẹ wọn na loni fun yiyanri ti ilẹ Apapa Oloye Oluwa yanri si rere.

Ki nwọn to dibo ni mo ti ni ọrọ lati so ṣugbọn ibi ti mo ni mo lọ ni ko jẹ, Makọli lo ran mi lọwọ pupọ, ko si Makọli na nile loni, ṣugbọn latari ọran Ilu yi lo njiya fun loni, enia lo ma tọju ile rẹ, ni yio si ma gbọ gbogbo bukata ti o ni lati ma gbọ ni ile rẹ fun u, ki a tilẹ ni o ni owo nile sibẹsibẹ

ko le dabi, ę ni lati ma ję ki a ma ran ara wa lọwọ fun anfani ara wa ati fun ire ilu wa ni. ki işe wipe ki a ma şe fari ete lęşo lasan wipe mo ni itara si ọran ilu.

A nsọ wipe ko si işę, o yę wipe ki a gbajumọ iyęn ki a kuro ni idi ọtę şişe, ko si nkan ti ęnikan le şe, tolotolo yinbọn idi lasan ni, nigbati ę fi dibo awon Ijọba ko sọ wipe nwọn ko gba ibo ti Dęmọ gęgę bi isokusọ ti awon olotę nsọ si ęgbę yi lara wipe nwon nta kanrangba si Ijọba ; ohun ti mo fę ki a şe akiyesi lọpọlọpọ ni wipe ki awon ti o nşişę mura giri ki a maşe gbe gbogbo ęru na le awọn agbalagba nikan lori.

Nigbati a fi dibo nihin ni ọdun 1923. Ologbe Shyngle ni ęnikini, Lọya Moore ni ęnikeji, Dokita Jones si ni ęnikęta, iwe Bibeli sọro kan ti o dabi owe wipe ęni işaju yio di ęni ikęhin loni nkọ Dokita Jones ti o ję ęni ikęhin ko si ni ihn loni nigbati nwon o fi dibo, şugbọn o di ęni işiwaju loni fun awọn aşoju męta ti ilu yan si Igbimọ Aşofin işę ti olukuluku ba nşe dajudaju yio jere rę, a mbę Oluwa fun awọn ęniti nwọn şęşę bọ si ibę yi, ki Ọlọrun ję ki nwọn le şe daradara, ki nwọn şe ilu yi ni rere.

## ỌRỌ ỌGBẸNI KADIRI IJAOBA.

Mo ki gbogbo nyin lọkunrin ati lobinrin, lọmọ de ati lagba, Ọlọrun ko ran nyin lọwọ, ki o maşe jęki awon ọta o ya wa pęlu ipa, gbogbo wahala awọn oloye wa Ọlọrun ko maşe ni asara fun wọn, Ọlọrun ki o ma ja awọn ęniti o mbę lęhin wọn.

Awọn męta ti ilu tabi ęgbę pi yan ni a fę fi nkan-kan si iwaju wọn, ire ilu yi ni a nwa gęgębi awọn na ti nwa rere ilu yi, ire ti awa ati awọn na nwa Ọlọrun maşe jęki a ri eyiti yio ni olukuluku wa lara eyiti o le ma bọ, Oluwa koni jęki ọkọ rę gunlę.

A mbę wọn latari ohun gbogbo ti o nni wa lara ki nwọn tunbo mura lati ma ran wa lowọ nipa rę, oniruru inira ti o le ma bọ, ki nwọn mura gidigidi lati ma şe iranlọwọ fun wa. ęnikan ko le fi ọwọ sọ aiya wipe gęgębi on tito bęni on yio şe, ki nwọn jọwọ ki nwọn gbidanwo awọ wọn ni nwọn nja, fun, awọn męta ti a nyan si Igbimọ ko to, ki nwọn tun ba ilu fi si si iwaju wọn ni Igbimọ ki nwọn tun le ju awọn męta na lọ, Doherty ọmọ arota ni, ọmọ mi ęwę lo si tun ję pęlu, Oluwa ki o ran n lọwọ lori gbogbo ileri rę, ki Ọlọrun si tun ran Moore lọwọ pęlu, a si tun tọrọ fun Jones, gbogbo bi Jones ti nja fun rere ilu yi ni ilu oyinbo li a ngbọ tabi a ti nwọn fi si wa leti ninu iwe irohin, Ọlọrun Olodumare ko ni jęki ęşin rę kọsę lọdọ Ijọba, ękuri iyowu ti nwọn ba sun nihin nwọn sun ti wa na pęlu, ki nwọn jọwọ ki nwọn tunbọ ba wa mura gidigidi, ki Oluwa lọra ęmi wọn fun wa o ! amin.

## ỌRỌ ỌGBẸNI SHACKLEFORD.

Ki işe ipo mi lati joko si ibi bayi loni, ohun ti o mu eyi wa ni wipe o şe Ọgbęni Moore Alaga ni arę die, a si ranşę si i wipe ki o gbiyanju lati wa o si sọ wipe on yio gbidanwo, o ti ba Dokita rę sọ şugbọn anu şe wa lati sọ wipe Dokita rę ko un u ni aye lati wa ati gęgę bi Moore papa ti kędun aile wa na.

Ọgbęni Moore ni on dupę pupọ fun gbogbo ęgbę fun ileri ti nwọn şe nipa on ti nwọn si ma ileri na şę, Moore sọ wipe nigbati a o ba tun pade Ọlọrun yio mu on wa si ęgbę, ki Ọlọrun şọ ipade wa.

Mo tọro gafara lowọ nyin, akọwe ęgbę Ọgbęni Jackson ko si nihin loni, ohun ti a si şe ni ipade igbęhin a ko ri ki o wa ka fun ęgbę nisisiyi, ohun ti a ti mba bọ ri ọkan, ti isinsinyi ọkan, ęgbe yi de arin işan kan, işan na a o la a ja lagbara Ọlọrun ipade ti a nşe ọkan ęwę, ipade ti oni ọkan, o tun yatọ, kilo mu eyi wa, a wa pade nihin loni fun inu didun lati yọ, o si tọ ki a yọ, a şe ohun ti o tọ tun ara ęn, ati fun ilu ęni.

Loni mo duro ni iduro alaga mọ si wa dupę lọwọ gbogbo ęgbę ati awọn ęlomiran ti o duro şinşin.

Nigbati a bęrę si wewe ogun, bi a o tişe ogun na si a ko mọ nigbati a kọkọ bęrę larọ, şugbọn ni gbogbo igbati a npilę ogun yi a ko i mọ bi yio ti lọ si nitori ọkan ko balę, şugbọn nigbati o di ipade ti a şe gbęhin nihin ni ọkan olukuluku wa to duro pe a o şęgun, mo dupę lọdọ Ọlọrun pe o fun wa ni işęgun na—Oloye Oluwa yio ba nyin sọro nisisiyi.

## OLOYE OLUWA.

Labari pọ fun wa losę yi ati pęlu ọrọ Ọgbęni Akisanya ti a ti mba bọ lati ọsę kęta ki a to wa parı rę lọsę yi, ko jęki a le ri owo yọgbe nipa ọrọ Oloye Oluwa ( Amọdu Tijani ) ati ọrọ Ọlọla Lọya Adebayọ Doherty, nitorina a fi eyi si ọsę to mbọ lagbara Oluwa ohun ti o dara julọ ni fun wa ni wipe o yę ki a ni ọrọ wọn lọwọ fun iranti ọjọ miran.

## ARỌKURO NGADABU.

Lati iwọn ọsę melo ni ojo Arọkuro ti nwọn ngbin igbado ęrun ti nrọ ni ile ati loko, o rọ pupọ li Eko nisisiyi to bę ti omi fi kun pupọ gbogbo ita kakiri lo si di şipin-şinpin, ki Oluwa şe ni ojo anfani o—amin !

---

## OYINBO OLOMI ILO, OMI ILO FĘ WO ILE No.......ONIBUDO STREET, LAGOS.

Awa tọ kasi ile *house* ti No.......Onibudo Street, Lagos, fun ęnyin P.W.D. ( *Water supply* ) ko şe akiyesi pe omi ilo fę wole na, ati pe omi-ilo na le

fun awọn enia to ngbe ile na ni amudi-otutu (*cold sickness*) tabi amudi miran ati je awa fẹ mọ tani yio k ile na bi omi ba wo?

Gẹgẹ bi ẹtọ ati ohun to yẹ fun awa ni lati sọ wipe omi ilo *pump* na, ko yẹ fun ibẹ arara, bi enia ko ba fẹ ba tẹni jẹ o.—Awa yio ma reti nyin.

Nigasikiya, omi ilo *pump* na ko yẹ bẹ arara, bi enia ko ba fẹ ba tẹni jẹ.

---

OKUTA ỌJA NIGBORO.

Kini orin ti gbogbo ilu Eko ati oke Ebu'e Mẹta nkọ lẹnu, ko si orin meji bi ko ṣe aita ọja. Kini wa mu aita ọja bayi wa, ọpọlọpọ wa lo ma nsọ wipe bi nkan oko ba bẹrẹ si to lati ka, irufẹ Cocoa, Ekuro, ati nkan miran, ọja yio dide, gbogbo iwọnyi dun lati sọ bẹ, oṣu October la wa yi, lati oṣu September to kọja ni awọn Agbẹ ti nta ọja diẹ-diẹ, ṣugbọn sibẹ-sibẹ pabo ni gbogbo nkan ti a nwi yi. Ẹn ti oba fẹ jadi ọrọ ti mo so yi, ko lọ si popo ita Balogun, ko gba ibẹ lọ si ẹhin ọgba, ko gba lọ si ita Agarawu titi de oju oto, pataki tilẹ ni ẹhingbẹti, gbogbo yin a ri wipe papa nigbogbo ibiti a wi wọnyi da paro-paro, ki lọ mu aita ọja yi wa, tabi ki lo mu awọn ajeji to wa ilu ti wọn ko wa mọ. Ẹjẹ ki abi ara wa, tabi nitori ki wọn ma ba awa ara Eko pin owo ori san ni, tabi nitori kini, ẹniti oba fẹ mọ riri on ti mọ nwi yi, eyiti o ba lo mọ oniṣowo kan yala dudu ni tabi Kora, yio rohin fun ọ iye ti wọn npa ṣulẹ. Opọlọpọ ni ẹru de fun to wa ni Banki ti ko le gba, eyiti owa nile lọwọ rẹ, o ma sun yẹn jẹ ni, ko to wa ba damọran wipe ko gba ti Banki, ọpọlọpọ awọn oyinbo oniṣowo lo mọ iye ẹru awọn oniṣowo wọn, ti wọn gba sodọ, ti owa di ẹru to nwọ awọn papa lọrun loni, ti yio jẹ ki wọn mọ iyi wipe, ki ṣe wipe awọn onibara wọn ko fẹ owo lati san, ṣugbọn nigbati ko ta, to jẹ wipe gbogbo owo on papa wa ni ori owo nkọ?

Ẹyin gbogbo ojiṣẹ Ọlọrun ilu yi, gbogbo ẹyin Ratibi Eko yi, gbogbo ẹyin adawunṣe gbogbogbo, ẹjọwọ ẹba wa bẹ Ọlọrun ko fun wa ni aiyi pada rere, nipa owo ni ọdun ni, ko fi oju anu rẹ wo wa, ki ọja wa ko le ta, ki ale ri apa ba nọ, loni yi bi ọja ko ti ta to, iyẹn ko ni ki owo Gari ko din ku, bẹni ako le ṣai jẹ gari lojojumọ-ki nfun yin ni ọkan si, ṣe gbogbo awọn awa Motor ni a npe ni ọmọ ọjẹka, ṣugbọn gbogbo awọn Ọlọka papa nkọ loni, jijẹkọ ni wọn njẹ omiran fun ara wọn nigbati awọn oni Motor ko ba ni owo ti wọn ma san to jẹ wipe ọka awin ni wọn ma ma jẹ, tani ma digbese, eyi fi han nipa wipe ọja ko ta nilu, ni idayi eṣi, gbogbo ilu nṣe ritiriti osi fi nhan wa wipe ọdun nbọ, ṣugbọn loni gbogbo rẹ lo pa rọrọ-Ẹba wa ṣe adura Ọlọrun a gbọ adura yin O.

Ohun pataki ti atun ni lati ṣe akiyesi ohun ni niap "Ajakalẹarun" to nbẹ lode Eko loni, gẹgẹ bi iku ti npo si ni arin wa, gbogbo ara ilu le ṣe akiyesi nipa ọran pataki yi, nitori pe ko si ni oju wa ni gẹgẹ bi iti n gọwe yi wipe ogun bayi lole wo san, tabi nkan bayi ni ale ṣe si ṣugbọn imọran ti olukulu u wa le da on ni pe bi ati ma ṣe iranlọwọ fun ijọba nipa ọ akọna ti a rope arun yi le buku, ọpọlọpọ ninu awọn edemukunrin wa ti ko ri iṣẹ ṣe ti wọn ko si fẹ ma rin rin agbanraye kiri ilu tabi ki wọn jẹ ọmọ jaguda ni wọn lọ wọ iṣẹ ni Plague Office iṣẹ ti wọn si wọ na nipe ki wọn ma ba Ekute kakiri ile gbogbo to wa ni ilu ọpọlọpọ ninu wọn wọn ki gba owo oṣu ṣugbọn wọn ngba owo lori Ekute ti wọn ba pa, nitori ki arun ma ma gberan siwaju mọ, nipa bẹ ko si ewu ka fun ẹnikẹni ti wọn ba dẹ pakute si ile oluwa rẹ ti pakute ba si mu Eku ki wọn ma yọ Ekute na sonu ṣugbọn ki wọn fun akọwe to wa dẹ pakute si ile wọn nipa iranlọwọ bayi awọn Oniṣegun ijọba wọn o ri ona tabi oye miran ti won le gba nipa arun yi—ọpọlọpọ ni oku ku ni ile rẹ ti ojẹ wipe arun ode yi lopa ṣugbọn ti awọn ara ile na ma fi eṣẹ fẹ, nipa irufẹ si salọ bẹ omu ki arun yi ma gbe-eran sile ti wọn ba salọ to jẹ wipe arun yi kan na lo ma ko ba awọn ti wọn mọ ọwọ ti wọn ko mọ eṣẹ irufẹ nkan bẹ ko dara, bi oba joko si ile rẹ awọn ijọba nitoto wọn omu iye ẹyin tẹ ku nile lọ si ile alarun ni Ikoyi wọn a si lọ tọju yin nipa bẹ arun yi yio dinku otitọ ọrọ koro ẹlomiran le lọ, olọjọ a deba nibẹ bi kadara oni yẹn tiri niyen, bo salọ ti titan ba ẹ ni ọhun wa ṣa ku, tabi tani oma fi aiku jọ, ẹ jọwọ ẹ wo oran "Ajakalẹarun" yi wo daradara, nitorina ẹfi oran yi si adura ki Olorun Ọba le ṣiju anu rẹ wo ilu wa yi, ko si jẹ ki arun ko lọ patapata, gbogbo ẹyin Oniṣegun ẹ gba ọran yi yẹwo, ki ẹ sori ara yin kodo, nitori arun yi tiwa nilu yi o nlọ si ọdun mẹwa ni ọdun miran a din ku, ni ọdun miran a posi Oluwa yio gba imọran yin, yio si gbọ adura mẹkunnu.

Gbogbo wa nilu Eko yi yio gbọ agogo ti Ọba Sanusi Olusi to lu nipa ti ọran orin owe ati orin is kusọ ti wọn nko kiri ni ode Eko loni yi, oyẹ ki gbogbo nkan wonyi ko dinku ni arin wa, o si ṣe kilọkilọ fun awọn ọkunrin ati obirin ti wọn jẹ alagbe tabi onirara osi daruko wọn ṣugbọn ohun ti a fẹ sọ ohun nipe ọran Ọtẹ to wa ni arin wa opin si meji awọn ijọ kan lowa ninu ti Ọba yi tọ si jẹ wipe bakanna ni wọn nkọrin bakanna, nitori Olotu iwe irohin Daily Telegraph lawa loye nipa orin ti wọn nko, ọkan ninu awọn onilu eyiti wọn npe ni Alapaṣerin on lo nlu ilu wipe "iwe aramu" bẹni ẹlomiran lo kọ orin wipe wọn ti mu "Ejo digi" bẹ si ni nipa ti Ọba wa Eṣugbayi Eleko Baba Layide wipe "Ayi lala ko le gbe Eṣu wa wo ilu" bẹni nigbati Ologbe Ibi unle Akitoye n so ni ati ọdun ninu ọdun kan awọn ara il rin wọn ko oko dani wipe oko re ẹsọ ko, ẹwọn oṣu mẹfa ko pani lebi, tani ma gbọ irufẹ oran bẹ ti inu rẹ ko ni bajẹ bẹni awọn kan, ni wọn ko dasi ew n apapandodo nitori ọran asọ ko asọ ko, gbogbo nkan

wọnyi o ndun yangba nigbana, nigbati awọn kan bọ lati Ọyọ nkọ iru fẹ orin ti wọn ko ba le tan nilẹ, a ko fi eyi ṣe ati lẹhin fun apakan ṣugbọn bi agogo ti wọn lu yẹn oyẹ ni oju wa wipe ki wọn tun ilu wipe orin korin nilati wọ ilẹ lati odọ apa kini ati apa keji nitori pe ki ṣe ohun ti owa ni ode Eko nisisinyi ni yẹn, ran owo ori ti a nsan yi o to wa ro, nitori ko si owo ni ilu, ẹniti o ni owo lowọ odi nkan rẹ dani giri, bi owo wa tabi kosi ẹyin ẹwo awọn ọmọ jaguda melo ninu wọn lo tun ri owo yọ ni apo ẹnikẹni bi enia de ọja ita Agarawu ni irọlẹ nibiti awọn ọmọ jaguda yi fi ṣe Head Quarter yio ri wipe bi aṣa awọn ọdọmọkunrin wa wipe "Nothing Doing" nipa bẹ ẹjẹ ki afi si adura wipe ki Ọlọrun Ọba ko ba wa to ọran ilu yi ko gun ko si mu Ọba Eṣugbayi Eleko bọ wa si ilu rẹ.

Ipade Dẹmọ ti ọjọ Satide gbogbogbo okun de ẹnu, ile kun ọna bo, ṣugbọn Alaga wa Ọlọla Eric Ọlawolu Moore ko le wa oṣe bi arẹ, ara Ijẹmọ gbe ra nilẹ ko dide, nitori pe irufẹ ipade bayi oyẹ osi tọ ki Alaga wa ko wa nibẹ ṣugbon owun ẹmi ṣugbọn ailera ni fun ara. Lori bẹ gbogbo enia ni ẹsẹ wọn pe ṣọṣọ asi yọ fun ara wa wipe ibo ti adi fun awọn ẹni wa mẹta ibo na yege asi dupẹ gidigidi lọwọ awọn ti wọn ṣe iranlọwọ fun ẹgbẹ yi. Nipa imọran ti a da fun awọn Igbimọ Dẹmọ a fẹ ki wọn gba yẹwo, nitori ki awọn ẹni wa ti wọn fẹ jade ki wọn ma le jade ati awọn ti wọn jade ki wọn le pada wa. Ki o ma si ọran wipe bi wọn ba fẹ lọ ki wọn ma lọ, ṣugbọn ki a gbiyanju ati pe wọn, ati awọn ti wọn nfa sẹhin ki abere lowo wọn kini wọn ri to, ada eyi ni imọran ni ti ko ba si wọ, afi ṣe ti ara wa.

Ohun pataki ti afẹ gbe ẹnu le fun imọran awọn aṣoju wa ti wọn nlo si Igbimọ Aṣofin afẹ ki awọn Igbimọ Ẹgbẹ Democratic Party ki won fun awòn ẹni mẹta wọnyi ki wọn fi sinu ibere wọn wipe lotọ Ijọba ko gba owo Bode lori nkan jijẹ mọ. osi jẹ ki nkan jijẹ to nti ilu oyinbo wa ko din ku, ṣugbọn kini bo ti jẹ wipe ọja ko ta ki wọn bere lọwọ Ijoba bi wọn le ba wa din owo Bode ṣile mẹta lori pọun kan ti wọn ngba si ṣile meji (15 per cent on Advalorem to 10 per cent) bo ya iyẹn le jẹ ki ọja ko gberi diẹ' nitori ṣile mẹta yi oga pupọ fun awọn oniṣowo wa nitori ere elo ni won ma jẹ ninu ẹru won yi fun odun boya owo to ba wọle ko ni po ṣugbọn lori rẹ wọn a tun ma finu ṣiro owo omi (Water Rate) owo ori (Income Tax) bi ijọba ba le din owo Bode yi ku, yo jẹ iranlọwọ pupọ fun awọn oniṣowo.

Ohun keji iyẹn ni kọbọ meji owo otitẹ (2d Stamp) lati fi iwe ranṣẹ si ilu ti ko si ni abẹ Nigeria, ki Ijọba jọwọ ki wọn ba wa din si kọbọ kan owo ti ati nsan ri, bi wọn ko tilẹ le din de ilu wọn papa ki wọn ba wa din de Gambia, Sierra Leone ati Gold Coast nitori bi won ba le di i de ilu wọnyi, diẹ diẹ ni imu ẹlẹdẹ fi wọ ogba ki wọn jọwọ ki wọn ba wa din owo yi si kọbọ kan, bi wọn ba ba wa ṣe eyi yio jẹ ki nkan bọsi aye rẹ bi ti atijọ, ki awọn aṣoju wa ki wọn fi eyi si ero yi wọn fi si iwaju Ijọba ti wọn ba de Igbimọ.

Ohun kẹta ti mo fẹ ki wọn tun fi si ero, ohun ni nipa ti awọn ọmọ Ile-Ẹkọ bi ọmọde ba di ọdun mẹrindilogun ko tun yẹ ile-iwe mọ, oni lati kuro, ki ṣe gbogbo enia lo ni ipa ba kanna lati ran ọmọ lọ si ile Ẹkọ ni akoko kan na, bi enia wa ni ilu oke, bi ọmọ rẹ ko ti to ọdun meje mẹjọ ko ti malọ sinu oko ko mọ oko riro daradara, ko ni bẹrẹ ile iwe ọdun melo lo ku, tabi iwe mole lo ma kọ ki o to di ọdun mẹrindinlogun, a si bẹ ẹnyin aṣoju wa, ki ẹ bẹ Ijọba ki wọn sun ọdun ti "King's College" de ọdun mejidinlogun fun gbigba ọmọ si ile-iwe, bo ba si ti to ọdun mọkanlelogun wọn le bere lowọ rẹ wipe ewo-le-wo, ọpọlọpọ ile-iwe bo ba mu ọmọ ọdun mẹrin de bẹ wọn ko ni fẹ lati gba, nwọn a ni ko si aye, jẹki o di kuọta miran bẹni wọn ma yi o po titi, ile-iwe ti ọkan rẹ mu yẹn ko lo ma lọ a fi omiran ti ọkan rẹ ko fẹ bẹni o dẹ le jẹ ki ọmọ yi joko lasan nitori na ẹ ba wa bẹ Ijọba, ki wọn ma jẹki ile-ẹkọ ọmọ wa di a fi agbara wọ o—Eyin yin aran o.

Njẹ ọpọlọpọ nyin lo ti fi orukọ silẹ ni Munisipa fun idibo ti ọdun 1929 gẹgẹbi a ti ma nṣe ni ọdọdun ki aseko Idibo to to, bo ba ti ṣe bẹ ma jafara, ọjọ pe tan—gbogbo ẹniti o le fi orukọ silẹ ni awọn ti owo to nwọ le fun ju tabi o to ọgọrun pọnwun, ẹniti o si ti ngbe ilu le ni ọdun kan, ẹniti o si wa ni abẹsẹ Ọba (King George, ẹniti a ko ti fi si ẹwọn ọdun kan, ẹniti ọjọ ori rẹ le ni ọdun mọkanlelogun ọrọ re o—Ọrọ wa di osẹ miran lagbara Baba!

"A! IKU DORO."

A gbọ ju gba nu ni a gbọ iku Ọgbẹni Izidorio Baretto, ẹniti o ku ni ile rẹ O.I Mill Street ni Eko ni ọjọ Sunday ijọ keje oṣu yi, ni ọjọ Tuesday Ọgbẹni yi wa ni ẹnu iṣẹ rẹ ni ṣhabu awọn oyinbo Standard Company ni Custom Street, ni were ni a gbọ iku, ni arin iye awa mbẹ ninu iku—ki Oluwa ko gbe si afẹfẹ rere—a si ba awọn ẹbi oloku kẹdun iku Ọgbẹni yi ni asiko ti irawọ rẹ ntan.

A tun ba Ọgbẹni Muritalabi Alhadji ti o nṣi ṣabu ni Ereko kẹdun iku ọmọ rẹ obinrin abileko ẹniti o jẹ ọmọ odun mẹdọgbọn ni aiye rẹ ti iku si mu lọ sorun apapandodo—a si ba Ọgbẹni wa yi kẹdun iku omo rẹ, ki Oluwa da awọn to ku si, kò si fi ọrun kẹ ẹniti o fi awọn ẹbi rẹ wọnyi silẹ lo—ki Oluwa si dari aṣiṣe rẹ jin—ki Oluwa si rẹ awọn ẹbi rẹ lẹkun.

"ILE-ẸJỌ GANRAN"

Lati ijo kini oṣu July 1928 titi fi di ipari oṣu September to kọja yi ni Ile-Ẹjọ ganran ti wa ninu

isinmi gęgę bi wọn ti ma nşe ni ọdọdun ni ijọ kini oşu October 1928 ni Kotu yi ti bęrę işę rę, gbogbo awọn Loya si tun mu işę wọn şe–Ọpọlọpọ awọn to gba ọlọfę lo si idalę ni ọna oke ati ọna oju omi, loko-lodo gbogbo wọn ni wọn si ti pada de, awọn to lọ si ọna Abęokuta bi ọmọ titun ni wọn ri nigbati wọn de, eyiti to lọ si Agbadarigi nişe lo pọn wę ę, Ọlọrun muję ki ęlufin nidi işę yin O. A şe yi şę mi.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ENIA KO DA BI ALLAH.

---

NIGERIAN RAILWAY, "KO DARA TO."

Ede ti o wa ni oke yi ni o nbę ni ęnu gbogbo ero ti o nwọ okọ-lę lati Lafęnwa lọ si gbogbo agbegbe oko Abęokuta ati titi lo de Eko lati ibęrę oşu yi ti awọn Alaşę ọkọ-ile ti fi kun ọkọ ero, ti nwọn sọ ọko Lafenwa di Sọbọ ti nwọn si din owo ęru wiwọn ati owo ori ku.

Nigbati a şe akiyesi ifikun ọko ati sisọ ọkọ Lafęmwa di sọbọ yi, a ri pe iyipada rere ni eyi ję fun anfani Ilę-Ęgba, a si ri pe eyi dara pupọ nitotọ, şugbọn ni gasikia a ko le şe aisọ bi ọrọ ode isişiyi ti awọn ewe iwaju nlo fun nkan ti o ku dię ki a to pe "Ko dara to." Ngọ si la idi rę fun aiye gbọ bi o ti şe ku dię ki a to; ireti mi si ni pe eyi yio mu ki awọn ti ęnu wọn to ilę ni Abęokuta ati ni Eko kọ iwe si awọn alaşę ọkọ-ilę lati tubọ ję ki o dara to.

Idi ekini ni pe ko si ọkọ ti yio ma kuro ni Lafęnwa ni ọsan ojojumọ ni iwọn agogo męta lọ si Eko, ti yio fun enia ni anfani lati ma lọ si Abęokuta ni owuro, ki a şe ohun ti a ni işe were ki a si pada si ọna oko (ti awọn Eko npe ni ọna ile) ni irọle.

Idi ekeji ni pe bi ọkọ sọbọ ba wa fun Ọja Ifọ yio ję a nfani ati iyanju pupọ fun awọn agbę ni Ilę-Ęgba: nitori enikęni le ma mu ęja on ę bi işu, gari, agbado ati ewebe lọ si Lafęnwa ni ọja Ademola da ki nwọn si ma pada ni irọlę si ọna oko pęlu irọrun:—Sọbọ sa ni ọko, a le gba iwe rę ni agbalu fun alo ati abọ ni ędinwo, pọ ni ęru wiwọn rę, bi o ba tilę je ęru ti o şe gbe ni ilę fęrę (28 lbs) ofę ni, apọ ekuro aranpa meji tabi męta ti işu tabi agbado kun inu wọn ko ju sisi lọ (6d) de ibikibi lati Ido de Lafęnwa. Ha! awọn Ọlọkọ ilę şe chun ara ati kisa nitotọ, şugbọn ko ti dara to.

ĘGBA-AGURA.

INA WỌLE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oşupa mi" ję ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yę ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le şęşę ma sọ ti awọn "Dęngę". Agbara rę pęlu agbara atanpọ ọdunrun abęla, dede ni, bi ọsan si ni titan rę ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Şango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric ję.

Orişi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidę.

Ę lọ yan ti nyin ni Şabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ęnyin ara-oke ati ilu miran, ę maşe gbęhin ki ę to ranşę ti nyin, ki ę ma ba j'oku ologbo.

---

JUST ARRIVED.

**WASU**

journal of the West African Students' Union of Great Britain.

**1/- per copy.**

**Obtainable at the office of :—**

**"TIKA-TORE" PRESS,**
**Bread Street, Lagos.**

# EKO AKETE

Eko, Saturday, October 13, 1928.

## ẸNYIN AṢOJU ILU EKO, GBANGBA L'Ẹ WA !

Gbogbo oworan Egun ni a tanmọ pe nwọn mọ itumọ ọrọ orin Oke yi nigbati egun kan nba npidan ti o si dabi ẹnipe aṣọ fẹ di lọwọ nipa pe ki apakan ninu ara rẹ han si ita nigbayi ni alubata rẹ yio sọ kọkọrọ si bata rẹ kikan ti yio si ma lu pe gbangba l'owa. Eyiyi yio mu ki egun na iakiji, lati ṣe atunṣe ki o ma ṣe ba awo jẹ :

A fi awọn aṣoju Eko ni Ajọ Igbimọ ofin *Nigeria* we egun yi, papa ni asiko ti Ilu ṣeṣẹ yan wọn sinu ajọ Igbimọ na. Loni alaisi irọrun to mbẹ fun Eko nipa oriṣiriṣi ofin miran ni o jẹ ohun ti o ni pupọ enia lara nisisiyi pẹlupẹlu ofin Owo-ori : a fẹ ki awọn Aṣoju mẹta na ṣakiyesi oriṣiriṣi ofin ti o mu inira dani yi ki nwọn si wa wọrọkọ ṣe ada lati mọ ọna ti nwọn yio gba lati bẹ Ijọba ki nwọn dẹwọ inira yi : owo omi ti Ijọba tabi awọn Munisiba tun fi'kun lẹnu ọdun diẹ sẹhin yi ko ṣai mu ọpọlọpọ awọn enia ni imu ọni-amunimada sibẹsibẹ awọn ẹlomiran mbẹ ti nkan wọnyi jẹ inilara fun gẹgẹbi awọn enia miran ṣugbọn ti nwọn nrun mọra kaka pe ki nwọn gbọjẹgẹ lati fi ohun ṣọkan lati bẹ Ijọba fun didin risan owo yi ku.

A woye pe awọn ti nwọn nhaya Ile gbe l Eko lode oni ju idameji Eko lọ awọn wọnyi si ni a rope owo-omi ti awọn Munisiba ti fi kun yi ati owo-ori nbawi ju : ile miran ti koti to nkan bi Sile mẹdogun ni hihaya ri ko ti fo fẹrẹ di £1 10 0 oṣu nisisiyi : ohun ti o si mu fifofẹrẹ bi afomọ yi wa ko ju bibu ti awọn onile bu si owo Ile hihaya wọn lẹhin igbati nwọn ba ti ro owo omi ati owo-ori ti Ijọba ti kesi wọn pe ki nwọn wa san.

Iṣẹ ẹnyin Aṣoju Eko kuro ni wasa, ipo ọla ti Ilu fi nyin si ki ṣe pe ki ẹ lo ni ọna "Talo ma mu mi" tabi ilo "A ho o, A bẹ-ntẹ". Ni iwọn igbati ẹ ba ti fi airoju ilu ṣe airoju ti ara nyin, niwọn igbati ẹ ba ti fi inira ilu ṣe inira ti nyin niwọn igbati ẹ ba ti fi airikan ṣe kan Ilu ṣe airikan ṣekan ti nyin, ani niwọn igbati ẹ ba ti fi aininudidun Ilu ṣe aininudidun ti ẹnyin papa ti ẹ ba si wọ ṣokoto giri lati ba ilu gbọn diẹdiẹ ninu inilara wọnyi nu ti ẹ ba si wa ni ipo "abọwọ gbọgbọrọ ti nyọ mọ-rẹ l'ọfin" kuro ninu ofin aninilara miran ti Ijọba tun pete lati so fun lilo ni arin wa, nigbana ni awa yio mọ pe iṣe aṣekara fun awọn eni ni ẹ ba lọ si Ajọ Igbimọ na, ki si ṣe ati ma fẹ fo bi akọ ọka ti ẹniti a gbe sipo ọla diẹ: ṣugbọn bobajẹpe ṣiṣe igberaga tabi ṣiṣe iṣẹ ilu ni yẹsuyẹsu ni ẹ ba lọ si Igbimọ yi, ki ẹ mọ daju pe iwa dida ilu ti o le tun ju eyi lọ kosi mọ ; nitorina ni Ilu ṣe nlu ilu bata yi fun nyin pe "gbangba l'Ẹ wa"

Ẹ tun gba ọrọ kan si; o yẹ ki awọn Aṣoju Eko wọnyi bẹ Ijọba lati kọ ile kan fun awọn Akuṣẹ ti nwọn nrin kakiri igboro; botiwu ko ri aworan Eleda ni nwọn sa jẹ gẹgẹbi olukuluku enia : lati igbati diẹ ninu wọn ti nsun si abẹ panu ni Ita Faji ti awọn ẹlomiran ninu wọn si nsun ni ikorita, tobẹ ti ọkan fi ku si ita gbangba ni Anikantamọ ninu ọdun yi, ko-si ẹniti o pẹkẹ lu ọrọ wọn ni mimusọ, o wa di igbati ọkan ku ninu wọn ki Ijọba to gbe oku na lọ, bẹ dandan, nwọn ki awọn Obi obinrin ti o ku na ku ewu lojọ kini, Agbalagba d'ọwọ ẹnyin Aṣoju Ilu Eko nipa ọrọ ti a ti mba nyin sọ bo yi a ki pe l'ẹru, ki a pe l'ọṣọ.

Gbangba l'Ẹ wa.

---

## Olusakin's Column.

**Mr. Herbert Morrison.**

**New Chairman Labour Party.**

London, October 5th.

Mr. Herbert Morrison was at Birmingham last night elected Chairman of the Labour Party in

succession to Mr. George Lansbury. Miss Susan Lawrence, M.P., was elected Deputy Chairman. Miss Lawrence will be the first woman to occupy this position. In the normal course she will succeed to the Chair after Mr. Morrison's year of office.

QUEEN'S COLLEGE, LAGOS.

According to *Nigeria Gazette* there will be an entrance examination at Queen's College on Saturday, the 20th October, 1928.

Applications for permission to sit for this examination should be sent to Mrs. Oyinkan Abayọmi, Godstone House, the Fields, Lagos, from whom all particulars may be obtained.

LEGISLATIVE COUNCIL.

A meeting of the Legislative Council will take place in the Council Chamber, Secretariat Buildings, on Saturday, the 24th November, 1928, at 10 a.m.

ON LEAVE.

Mr. E. W. M. George, Cashier, Bank of British West Africa Ltd., is on two months' leave as from the 1st September, 1928. He had been touring the Cameroons, Duala, Victoria, Tiko and Fernandopo, Oshogbo, Ilesha and Ile Ifẹ and arrived Lagos last Friday the 5th instant. Ẹ ku abọ.

MR. G. W. PARKINS.

Mr. G. W. Parkins, 1st Class Binder, Railway Press, has been on six weeks' leave, as from the 29th September, 1928.—A happy man.

ON LEAVE.

Mr. A. B. Ọjọmu, 1st Class Compositor, Nigerian Railway Printing Office, Ebute Metta, is on one month's leave, with effect from the 8th October, 1928. He hopes to spend his leave at Kano, and Ibẹju with Onibẹju of Ibẹju.

ANNUAL HARVEST.

Harvest Thanksgiving Service was held at the United African Methodist Church, (Ẹlẹja), on Sunday the 7th October, 1928, at 3.30 p.m.

Rev. Arthur A. Henry preached a very impressive and most powerful Sermon to a large Congregation numbering about 2,000, quoting his text from Genesis 24, verse 47. The Officiating Clergies were the Rev. Supt. D. A. Hughes, Rev, D. A. Bababunmi, the Pastor of the Church, Rev. J. F. Ogunko, Rev. E. Ayọ Salu, Rev. J. O. Shopekan, Rev. N. T. Williams and Rev. G. Hayes Williams.

We congratulate Mr. J. A. Oshodi, the Church Leader, the President M. O. Allen, Mr. Ọlamide Ajayi, the Harvest Committee members, the Secretary and all concerned for this grand affair.

At the close of the Service and Harvest sales the total receipt amounted to £350

BIRTH.

Mrs. Abiọla Byass, wife of Mr. C. O. Byass, was delivered of a female child on Thursday, the 4th instant. It is reported that both mother and baby girl are doing well. A ba ẹ yọ.

Ki Oluwa Ọba Onikẹ Ọba Onigẹ, ko da ọmọ na si.

DIVORCE SUIT AGAINST BARRISTER.

ỌBAFẸMI *versus* ỌBAFẸMI.

**Wife alleges she was turned out to make room for Paramour.**

In the Supreme Court of Nigeria on Tuesday the 9th day of October, 1928, before His Honour the Chief Justice Sir Ralph M. Combe, KT., a petition for dissolution of marriage and for such further and other orders as may be meet was argued at the instance of Mrs. Matilda Ọmọpẹ Ọbafẹmi, wife of Mr. Charles Harrison Ọbafẹmi, Barrister-at-Law.

The case was not defended.

The Petitioner, Mrs. Matilda Ọmọpẹ Ọbafẹmi who was Represented by Mr. S. Ayodele Thomas, (Inter L.L.B., London) Barrister-at-Law, said in her evidence that she was married to Mr. Ọbafẹmi the Respondent on the 29th April, 1919, at Christ Church, Lagos, and that he always beat her and inflicted a wound on her left wrist. The Petitioner stated further that on one occasion she had to be turned out of the house by Respondent and her room locked up for six good months during this period she had to stay with one Mr. Mends Cole, and that the Respondent did live with another woman by name Ellen Eyinlẹ Ọlaside in the same house. Mr. Mends Cole a popular jester and comedian who, on this occasion styles himselg "Commission Agent" gave evidence at the instance of the Petitioner but his evidence was so diametrically opposed to, or at variance with that of the Petitioner that it was thought he would receive his "call fee" from the Respondent. The case was immediately adjourn-

ed fro the next morning at 9 a.m. in favour of the Petitioner for further evidence to corroborate her own.

On Wednesday morning as the Petitioner was unable to produce any more witness to support her allegations Mr. Thomas who represented her explained to the Court the difficulty involved in getting witnesses in a case of this nature and that the Petitioner is a quiet woman going, non complaining to anybody besides Mr. Mends Cole whom she stayed with until about two months ago when she left the house.

His Honour the Chief Justice expressed satisfaction with the evidence placed before him and the Petitioner was granted a *Decree Nisi* with costs against the Respondent.

We congratulate the Counsel Mr. S. Ayọdele Thomas on this case.

OLUŞAKIN.

---

## ỌRỌ ỌGBẸNI : SAMUEL AKISANYA,

(APA KETA.)

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

*( Democratic Party's meeting September 22, 1928. )*

Ni ọdun karun nigbati awọn ara ilu Kalaba (Calabar) yio fi mu ẹniti nwọn yio fi şe Aşoju wọn ni Igbimọ, eniyan meji Ọgbẹni Henshaw ati Ata Amonu lo fẹ lọ, nigbati nwọn dibo fun wọn, ẹyọ ibo kan pere ni ti Ata Amonu fi tayọ ti Ọgbẹni Henshaw nipa eyi ni Ata Amonu fi le lọ, ti o si gba ọdun marun ni Kansulu ti nko ba dibo mi fun Loya Moore Loya ni yio le lọ, nitorina ki a tilẹ ni ibo ti a fẹ di lẹ te yi ki Loya Moore gba ọdunrun, ẹwẹ ki Ọgbẹni Bagan Benjamin gba ọdunrun bakanna, ti mba fi ibo ti emi kan şoşo kun ti Benjamin, ẹnyin na le mọ gẹgẹbi yio ti jẹ.

Gẹgẹbi mo ti sọ wipe mo mọ a Lọya Moore sọrọ bi Aşoju wa ni Igbimọ-Aşoju.

Ni ọdun karun Lọya Moore sọ wipe ki ilu yan on si Igbimọ lati ru ẹru ilu lohun, iwe ileri rẹ, ti o şe nigbana o mbẹ ni apo mi bi mo ti duro yi, ti Ọgbẹni Lọya Shyngle, ati ti Dokita Jones mbẹ lọwọ mi pẹlu.

Ninu iwe ileri ti Lọya Moore şe, o sọ sibẹ wipe ti on ba de Kansulu on yio sa ipa on nipa ẹkọ awọn ọmọde gẹgẹbi o ti jẹ wipe ẹkọ wọn ko to, bi ti atijọ, o si tun sọ wipe on yio sọlu oran Kotu Igereko, on duro lori meji yi na, Lọya Moore mbẹ nhin loni, o si ngbọ ohun ti mo nwi yi.

Nigbati Lọya Moore de Kansulu ko şuja gbogbo ileri rẹ mọ to loju ti wa.

Ọgbẹni Lọya Shyngle ẹniti o tun jẹ Aşoju wa lo da ọran ẹko-şukuru na silẹ ni Kansulu o si mura lati şe fitafita nipa rẹ, ni ọjọ kejila osu *February 1926* ni nwọn sọrọ nipa ofin ẹkọ yi ni Igbimọ, Ijọba si mura lati taku lori ofin nwọn şe akatakiti rẹ, ki a to da lọ wọna, nwọn fi ipinnu ofin na si inu oşu mẹta (*May*), o ku ọjọ mẹtale-lọgbọn ki nwọn tun pade ni Loya Shyngle fi lọ jẹ Ọlọrun ni pe, ni Shyngle ko fi lẹ si nkankan si ofin na mọ, nibẹ ni Loya Moore ko şuja ọran na, bibẹkọ o di ipade melo ti Loya Moore pe awọn Ọga Tişa ile-ẹkọ ti o ba wọn jiroro nipa rẹ? Tabi o di igba melo ti Loya Moore fihan ẹgbẹ yi pe tayi ni wahala ti on şe nipa ọran ẹkọ yi ni Kansulu? Ọrọ pọ ti mo fẹ sọ loni yi şugbọn ngo ke kuru, bi o ba şe wipe Dokita Jones mbẹ nihin loni iba dun, nitorina o fi iyoku pamọ, (gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ :—ni ma sọ, gbọ awọn mura lati gbọ) ko si oye ti Loya Moore ko mọ nipa ọrọ ile ẹkọ, bi ọmọ ko ba to ọmọ ọdun marun nwọn ki yio gba ni Şukuru, bẹni ẹwẹ bi ọmọ kan ba si to ọmọ ọdun mẹrindin-logun nwọn ki yio gba si ile-iwe mọ, loni gbogbo ọran yi Loya Moore ko şe fitafita kan ti o ni lari nipa rẹ, a nlẹ Moore, o si nfẹ ki a dibo fun on, bẹni titi ọdun marun fi pe yi, a ko mọ wahala ti o tun şe nipa Kotu Igbereko, ni Igbimọ ti nwọn şe gbẹhin yi ni Ata Amonu ti Kalaba gbe ọran na dide, ki Loya Moore to şẹşẹ sọ wipe on gbe e lẹsẹ, ni ibẹ lo ma ti wa lati ọjọmọjọ yi wa.

Emi yio sọ fun nyin wipe Loya Moore şiwaju Ata Amonu nipa işẹ Loya, bẹni o si şiwaju Ata Amonu de Kansulu, ọdun karun yi ni Ata Amonu şẹşẹ wọ Kansulu, o si ti ri oye Kansulu daradara lati ọjọ gbọrọ, mo wa mbi ẹnyin Ojoye, ọkunrin ati obinrin lere tani ẹniti o ba jẹ aşiwaju ninu awọn mejeji nipa ọran na?—Ẹgbẹ :—Moore şugbọn ti a ba yẹ gbogbo ọran na wo, gẹgẹbi Moore ti jẹ ọkan ninu Olotu ẹgbẹ yi ko mu ogiri si gbogbo ileri rẹ, be o si tun nfẹ ki ẹgbẹ tun yan on lẹnkeji, ẹ jẹ ki a dibo fun un.

Nigbati rogbodiyan ofin—Owo ori bẹrẹ, a ko mọ igba ti Moore wa si ipade ẹgbẹ yi lati ba ẹgbẹ jiroro; nigbati awọn ẹgbẹ yi yio fi şe ipade nipaşẹ ọran owo-ori na ni ẹnikan ti o jẹ pataki ninu awọn Olotu ẹgbẹ (ẹniti nki yio daruko rẹ) kọ iwe si i li o si bere lọwọ rẹ pe ewo lo nşe nipa ọran ti o delẹ ra lati le wa şe ajọ, nitotọ o da wọn lohun nipa iwe ti nwọn kọ si i nigbana wipe, on kosi ninu ki nwọn gba owo-ori na, nitotọ Ọgbẹni Moore wa si ipade ti ẹgbẹ yi şe nigbana, emi papa si wa si ajọ ni lọjọ na, a sọ fun awọn Aşoju wa mẹtẹta na Moore Jones ati Caulcrick nigbana wipe a ko fẹ san owo-ori, a sọ fun wọn wipe ti nwọn ba de ohun ki nwọn ba wa kọ ofin owo-ori na, gbogbo wọn ni nwọn si jumọ lọ si Igbimọ,

awon si so wipe ofin na ko wo, şugbon awon Ijoba nso wipe awon ilu pęp̣ẹp̣ẹ dede nsan bawo ni Eko ki yio fi san.

Ijoba yan awon mewa ti owo-ori na, ninu won ni Olola Loya Moore wa, nwon si jihin ipinnu ti Igbimo, a so fun won wipe Ijoba ko fi idi toto han bi nwon tişe ni lati gba owo na, a si so fun won wipe nipa yi a ki yio le san owo na.

Nitoto lehin ti Loya Moore kosi ni ile ti o lo si ilu Oyinbo ni Ijoba so ofin owo-ori na di gbigba, o si gbo lohun wipe nwon so ofin na nigbati o si bo ilu Oyinbo a ko ri fitafita kan ti o şe si idi re, nipa eyi gbogbo ileri ti o şe ninu iwe re ki a to dibo fun un ni odun karun, kosi nkankan ti o şuja nibę mo, a ko le ma ka oniruru gbogbo ohun ti a ni ireti pe yio şe ti kosi kobi ara si nkan ninu won mo, eyi je ohun ti a ni lati fihan on daradara, şugbon ko ni ki a maşe dibo fun un, bi a ba dibo otę yi fun un, bi o tun so wipe on yio tun lo si Kansulu ni ojo omiran, bi a ko ba ri dasi, ao tun dibo fun bakanna.

A ko le ma şiro işę ribiribi ti Dokita Jones şe fun wa ni Igbimo ti o yę wipe ki a ma kan sara si i.

Ninu awon ohun pataki ti Jones şe, o fi si iwaju Ijoba wipe ki nwon şi ile-alarun ti Ereko bibękọ ki nwon tun ile-Alarun ti Ita Ęlęiyę ( Massey Street ) şe nwon ta oro na kulę şugbon loni nko larin odun marun gbogbo wa ni a mo iru ipo ti ile-Alarun Ita Ęlęiyę na wa loni, bę ni o fi si iwaju won wipe ki nwon tun Kereni Ikoyi şe, wonn tun ta oro re kulę, a ri iru ipo ti Kereni na mbę loni, mo le ka to mejila fun nyin.

Ęnyin okunrin ati obinrin, bi oro Moore ati Jones tilo ni iyen fun işę olukuluku won ti nwon fi odidi odun marun şe fun ilu ni Igbimo-Aşofin, şugbon bi "a ba yo ipin ni oju ti a ko ba fi han oju, oju na a ni on ko şe ipin lojo kan ri."

O da mi loju wipe ti gbogbo wa ba dibo fun Loya Moore, ęniti o nfę ki a dibo fun on lati tun lo si Igbimo, yio mo nisisiyi lati mura si işę re siwaju gęgębi ilu ti nfę, o si ni lati mo wipe a nfi oju ba olukuluku won rin, gęgębi nwon ti nşişę won si, bi ę ko ba dibo fun mi, ko paladanu ohunkohun, nitori ę ni laii ranti pe ki a to dibo fun un ni odun karun, ni awon Ijoba ti fi owo arawon yan sinu Igbimo na fun odun męfa, ti o si şişę re daradara, nitorina ęto wa ni wipe ki a dibo fun un, şugbon oro ti a mba so yi, a nso o fun un, ni oro ti omo le ba baba re so, a si ro wipe didibo ti ao dibo fun yi, on papa ki yio jęki a tun ri ohun ti yio ko ilu ni ominu mo, bi oro ti a ni so nipa Ogbeni Moore ni iyen.

Wayi o, oro Ogbeni Doherty oro die ni a fę ba so nipa yiyan ti ilu yan an pęlu, nko ni oro aanindanin pataki lati so nipa re, nitori odomode awa na ni ati pęlu sawawu kanna ni a je, ti a ba ni ki a ma soro itakanragbon kan si i, arawa ni a nta ka iraugbon si.

Nisisiyi oro ti Duhati duro ni iduro ęniti o fę şi ilękun fun awon odomode lati lo si Igbimo-Aşofin.

Ti a ba tilę gbagbe rę gęgębi işę Loya ti o nşe, a ha le gbagbe baba rę Ogbeni wa Doherty papa baba rę je Olowo ni ilę yi, n torina a ni lati duro ti Loya Duhati giringiri.

Şugbon lona miran gęgębi baba rę ti je Olowo, mo ni nkan omiran ti mo le pe nija, ki a tilę ni a ki kowe tabi ki a soro, mo le gbe e lulę, şugbon kini o, omo Olowo le nşe, baba rę si ran si ilu Oyinbo lati lo ko ęko, on papa si je Olowo fun 'rarę, " yęyę ko ni işęta kosi ni idi ęşin bi o ti to nyęn."

Ohun pataki ti yio tun mu wa dibo fun Ogbeni Duhati ni wipe a kole fi oju omode wo o nitori ęnikan kole mo iru itu ti o le pa ni Igbimo-Aşofin, gęgębi o ti je wipe gbogbo işę ribiribi ti o nşe ni Igbimo ti ilu ni a nri, gbogbo wa ni a mo aseko awon bi Ologbe Debayo Agbebi Wonlę-wonlę, Ogbeni Folarin ati Dokita Savage nigbati nwon mbę ni Igbimo ti Munisiba yato si ti akoko yi.

Mo ro wipe ę o ranti nigbati ao fi dibo fun Dokita Jones ni odun karun, opolopo awon ęlomiran lo şe tiko ki nwon to dibo fun un, wipe kini Dokita le mo nipa nkan yi, şugbon loni nko o, Jones na lo tun npada şe ęto ti a ko lero lojo kini fun wa loni, nitorina mo pe gbogbo wa l'omode ati l'agba pe ki a dibo fun Duhati, "Agęmo ni on bimo on na, ai mo 'jo ku si i lowo.

*( Koi ti pari. )*

Emi ni ti nyin nitoto,

KEKERE-AWO.

---

### From Tour Of Inspection.

The Honourable the Administrator of the Colony Major W. Birrel Gray arrived Lagos on Wednesday the 10th instant from tour of inspection.

---

### Arrivals.

By the R. M. M. L. "Accra" which arrived last Thursday, the 11th October, 1928, Miss Ibironke Macaulay, daughter of Dr. Magnus R. L. Macaulay M.B., C.H.B., D.T.M., L.M., and Miss Omotuude Moore, daughter of the Honourable Mr. Eric Olawolu Moore, B.L., M.L.C., when the former went for Educational Studies and the latter for training in Midwifery after finishing her Education. Alafia kę de bi.

OLUŞAKAN.

ORI IV.

### IṢẸ.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KEJIDILOGUN.

Ni sa tiwa ni Ebenezer Elliot nṣowo ọpa irin ni ilu Sheffield, ninu eyi ni o ṣe ọpọlọpọ ninu awọn iwe arofọ orin rẹ; Owo na ti o nṣe gbe tobẹ ti o fi ri owo kojọ ti o si wa ṣiwọ owo ṣiṣe: o kọlọ si ilu oke nibiti o kọ ile; nibẹ ni o si ngbe titi o fi ku.

Isaac Taylor ti o ṣe iwe ti a npe ni "*Natural History of Enthusiasm*" darade ti iṣẹ ẹrọ; on ni o ṣe kọkọrọ irin ti a fi nfa ọti beer lati inu agba jade (*tap*) ati ẹrọ ti a fi ntẹ iwe tabi aworan sara baba eyiti awọn ti o ndara sara aṣọ funfun ni Manchester nlo yanturu.

Awọn ti o jẹ pataki ninu awọn iwe ti John Stuart Mills kọkọ ṣe jẹ awọn eyiti o nkọ nigbati o ba ṣiwọ nigbati o nṣiṣẹ ibode ni East India House—nibikana ti Charles Lamb, Peacock ti o ṣe iwe *Headlong Hall* ati Edwin Norris ti o ṣe iwe nipa ipilẹ ede, gbe ṣiṣẹ akọwe.

Nigbati Macaulay nṣiṣẹ *Secretary for War* ni o kọ iwe ti a npe ni *Lays of Ancient Rome.* Gbogbo wa ni a mọ pe awọn iwe daradara ti Mr. Helps kọ jẹ eyiti a le pe ni "Iwe ti a kọ nigbati a ba ṣiwọ lẹnu iṣẹ."

Ọpọlọpọ ninu awọn ọkọwe wa pataki ti o ṣi wa lorilẹ jẹ awọn ti o wa ni ipo pataki ninu iṣẹ ilu—awọn bi Sir Henry Taylor, Sir John Kaye, Anthony Trollope, Tom Taylor, Mathew Arrold, ati Samuel Warren.

Mr. Proctor, ọkọwe orin—"Barry Cornwall" ni gbogbo enia mọ ọ ju, jẹ agbẹjọro ati ẹniti o nṣe ẹjọ awọn were. Boya eredi alajẹ yi jẹ ọkana ti o mu ki Dr. Paris ma fi orukọ ara rẹ si iwe ti o ṣe eyiti a npe ni *Philosoy in Sport made Science in Earnest*—nitoripe o foya pe bi wọn ba mọ pe on ni o ṣe iwe na, eyi le ba iṣẹ on wi. Nitoripe iwa awọn enia ni iwa na ṣi wa lara awọn bọkini ilu, pe enia ti o ba ṣi iwe ati eyiti o ba tilẹ jẹ pe iwe orin ni o ṣe, ko le ṣe, iṣẹ kankan

Sibẹ a ri i pe bi Sharon Turner ti jẹ Ọkọwe-itan ti o gbamuṣe to, ko ni ki o kẹrẹ lọna iṣẹ rẹ bi amofin; ẹwẹ, awọn tẹgbon taburo Horace on James Smith ti o ṣe iwe *The Rejected Addresses* jẹ onu ninu iṣẹ wọn tobẹ ti a fi yan wọn si ipo nla clowo geregere, ipo amofin fun *Admiralty*, eyiti nwọn si ṣe daradara.

Nigbati ologbe Mr Broderip agbẹjọro nṣiṣẹ adajọ ile ẹjọ kekere ni London ni o bẹrẹ si kọ *Natural History*, gbogbo asiko ti ọwọ rẹ ba dilẹ ni o fi nkọ o. Laika ọpọlọpọ awọn iwe pataki ti o ṣe, papa eyiti, a npe ni *Zoological Recreations* ati *Leaves from the Note-book of a Naturalist*, o kọ iwe aṣayan—aṣayan pataki nipa ẹkọ yi sinu *Penny Encyclopaedia.* A sọ nipa rẹ pe bi o ti ṣe pe gbogbo akoko rẹ ni o lo fun ṣiṣe iwe wọnyi ati fun ẹgbẹ rere ti a npe ni *Zoological Society* ti o wa ni Regent's Park eyiti on na jẹ ọkan ninu awọn ti o pilẹ, sibẹ kikọ ẹkọ wọnyi ko di iṣẹ ti o nṣe lọwọ, bẹni a ko ṣi gbọ pe, a ti ohun kan ka si i lẹsẹ tabi pe o da ẹjọ kan ko da a rere.

Bi Broderip ti kunri mọ ẹkọ ti *natural history* bẹna ni ologbe Lord Chief Baron Pollock kunri mọ ti *Natural Science*, o nfi iṣẹ aworan viya (*Photography*) ati ti ẹkọ iṣiro pawọ: o si gbo lọna mejeji.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

TO LET.

**Use Yaro for your baby!**

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies.' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d & 2/3d.

**Increased health for 3/- only.**

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers.
Price 3/- per bottle.

**A chance for female sufferers.**

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness. Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs, cockroaches, etc., etc.
1/- and 1/6d per bottle.

**Anti-Gon Pills.**

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills--a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

Glaxo (large and small sizes)
Vitafer—Brain Tonic
Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
Pile Pills 1/6
Vibrona Wine 7/6
Lactogen
Kalzana
Effective Pile Remedy 7/6
Back and Kidney Pills 2/-
Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office:*—88, Broad Street, Lagos,
*Branches:*—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109, Griffith Street, Ebute Metta.

## White's Golden Male Tonic

(DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.* –NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.
Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy for Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILN ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pinọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER.

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Ioloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

**A Trial is Solicited.**

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

**TO LET.**

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to —

**A. B. Williams,**
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmi ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.